IJOBA OMINIRA BERE NI IWO-ORUN ATI ILA-ORUN

Drink Coca-Cola

SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

**Olomi Agbo**

Bami şe olomi ajiye a ye nipere on nwo tirę lodo. Piri ni olong oji a ki bi okunrun eiye loti ite oa mi şe, agbo kelębę, agbo iko, agbo oju, agbo ęsanri Baba mi şe o, olomi aibe.

VOL. IX No. 532. ELETI - OFĘ LAGOS, SATURDAY, AUGUST 10, 1957. KOBO MEJI (2)

# Ijoba Ominira bere ni Iwo-Orun ati Ila-Orun

Ni ojo kęjo oşu August, 1957, ni Ijoba Ominira bęrę ni ipinlę Iwo-Orun ati Ila-Orun - eyi ję işisę pataki irin'ke-rin'do wa fun wahala lati so ilę Nigeria wa yi di ominira gbogbo-gbo. (Independence for the Federation of Nigeria.)

ORI OGOGORO

Ade ori ogogoro kini ni ilę Nigeria nipa ominira ipinlę Iwo-orun ati Ila-orun eyi ję ijagun-m'olu pataki fun awon akonilę wa, o si fi han fun gbogbo enia ri gedegbe pe işę ti a w o n aşiwaju wa ti nşe a'i eyiti nwon nşe lowo-lowo yi k i i ş e işę kekere. Akoba ti a bęrę si eun lati nkan bi odun męfa s'ęhin ni o ku eyo işisę kanşoşo pere ki a de ori oke na, ao si de'bę pelu o g o Olorun.

KILO NIĘ IJOBA OMINIRA

Ijoba ominira ni wipe, nisisiyi ni ipinlę mejeji, Iwo-orun ati Ila-orun, ko tun si wipe ki Gomina ma paşę lori ohun ti akonilę wa ba fę şe ni ilu w a tabi ki Gomina kan tun ma şe atako idilowo wipe ki ohun ti awon aşiwaju wa ro si ęto lati şe duro laiko nişe mo. Eyi nikan ko, ko tilę ni si Gomina ti yio tun ma joko gęgębi alaga larin awon aşiwaju wa mo- awon akonilę wa (Premiers) ti Iwo-orun ati Ila-orun ni y i o maa ş e alaga ajo igbimo a w o n Opomulero (Ministers) wa.

Eyi ti han wipe bi a ba ni ifowo-sowopo şe i ş ę ilu wa pelu ifę ailabawon; laisi ani-ani, ijoba ominira ti gbogbo-gbo ti a njijadu fun ilę wa, kęlęlę ni yio to si wa lowo laiko ni si gbon'mi si omi koto.



DR. NNAMDI AZIKIWE
ALAKOSO ILA-ORUN



OLOYE OBAFEMI AWOLOWO
ALAKOSO IWO-ORUN

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital - £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

# Immam Ganiyu Thompson D'olegbe

Immam yi ję Alufa ti igbesi aiye rę dara pupo. o bęrę ęko ninu ile kewu Alufa Bello ni Idita. Nigbati o ba pada de lati ile Kewu, y i o lo k o ę k o ile-ęko ninu ile-iwe Breadfruits nigba a i y e Headmaster Weeks.

Nigbati o jade kuro nilewe o bęrę işę labę awon O y i n b o Olęko Elder Dempster ni erekuşu Iddo ninu odun 1916. O fi işę silę lati bęrę owo şişe fenra re, o koja lo si ilu Kano.

Dide ti o pada de lati ilu Kano, o tun bęrę işę labę awon Oyinbo Alamotękun ( B.O ) nibena işe owo şişe l'o mu ę lokan rę. o fi işę G.B.O. silę, o tun koja lo silę Sokoto l'oke Oya.

Ko pę pupo lęhin ti o pada de ni awon ti i ję oye Lemomu sinu Mosalaşi Idita. A b i i lodun 1889, o si ę enikan ti o lokiki gidigidi, o ni Osi Giwa ę bę B.M.C. o j ę oye Lemomu ninu odun 1951, o si ku ninu odun 1957.

Awon enia męta ti ati fi orukę won siwaju nisisiyi fun aye Lemomu to si silę ni Mosalaşi Idita lati ropo Olegbe yi.

Ęnikini ni Ogbęni Isau Lasisi

ęnikeji ni Ogbęni Nutu Williams

ęnikęta ni Ogbęni Yisa Onigbanjo.

Oba ko ti ori ęşę rę jin.

# Isokan Ile Nigeria Ni A Fe



Awon ti e nwo ninu aworan yi ni awon asiwaju wa ti nwon lo se eto ominira ile Nigeria nilu oyinbo awon ni a nwo yi, lati owo otun si si owo osi. Alhadji Sardauna Sokoto, Premier ile Hausa, Oloye Obafemi Awolowo Premier ile Yoruba, Sir Allan Lennox Boyd, Sekiteri agba nilu oyinbo, ati Dokita Nnamdi Azikiwe, ki Olorun ba wa lo wo sinu eto na.

*Ara* awon eto ti awon asiwaju wa nwonyi se na ni isodi-ominira lati ma da ijoba ara eni se, eyiti awon ijoba Iwo-Orun ati ijoba Ila-orun bere lojo kejo osu ti a wa yi.

Sugbon ki apapo Ile Nigeria to di ominira na pata-pata, o di odun 1960. Lodunni, ni ominira na iba yanju kedere, sugbon nitori ti awon Hausa ko iti lo siwaju ninu iselu, ni ojo na se sun siwaju.

## Adajo ko gba iduro fun Alhadji Dantata

KANO. Ha! ose, isale ọrọ lẹgbin nitotọ. Alhadji Mahmudu ti o nṣe ọmọ bibi inu Alasan Dantata, ẹniti a gbọ wipe, ko si olowo kan ni igboro Kano ti a le fi ṣe ẹgẹ rẹ ni awọn ọlọpa ka ẹrọ ti wọn fi nṣe korẹnsi ẹlẹyọ-kan Poun marun-marun ati on ati ẹrọ na, ni ọlọpa ba ko wọn, nwọn si fi Alhadji na si itimọle.

Lọya rẹ lọ duro fun, o si pada sile rẹ. O fẹrẹ maiti dele tan nigbati awọn ọlọpa tun ki mọlẹ wipe awọn ko le gba iduro rẹ mọ Adajọ kotu kekere ti o kọkọ gba iduro rẹ taku wipe, on ko le gba iduro rẹ mọ nitori irohin kan ti on gbọ.

Eyi ko tẹ Lọya na lọrun. lo ba tun ṣe iwe lọ siwaju adajọ agba, Lọya Alhadji Mamudu ati agbẹjọro fun ijọba tun tako ara wọn. Bi ekini ba fi ofin lelẹ wipe Adajọ ni lati gba iduro fun Alhadji na, agbẹjọro ijọba yio gbe ofin rabata miran ju silẹ ti Adajọ ko fi ni lati gba iduro fun Alhadji na.

Bayi ni awọn amofin mejeji bẹrẹ si ba ara wọn ja'gun ofin, titi Adajọ fi gba wipe, gẹgẹbi ofin ti wi, on ko le gba ki a duro fun Alhadji na, ipade ẹjọ na di ọjọ 20, oṣu Aug. 1957.

## Kini Alufa Ti Rin Ki O To De Odo

ETI ỌSA. A gbọ irohin wipe Alufa Ṣọṣi kan ti o nṣe wasu ninu Ṣọṣi, o wipe, ẹnyin ara mi ọwọn, Jesu sọ wipe, ẹnyin apẹja nwọnyi, ẹ wa sọdọ mi, emi yio si sọ nyin di apẹja enia.

Ọkan ninu awọn si bere pe, Alufa, bawo ni enia ti ṣe le jẹ apẹja enia lai kọkọ jẹ apẹja omi tẹlẹ? Alufa dahun pe, eyiyi ko ṣoro fun Jesu lati ṣe, bi o ba ti jẹ apẹja enia iwọ yio le pa ẹja ti omi. Awọn ijọ na si jiyan pe awa ko le gba eyi yi, nitoripe gbogbo wa ni ọdẹ omi, asimọ bi iṣẹ na ti ṣoro to fun ẹniti ko kọ iṣẹ na.

Kini Alufa gbọ bayi si, o bọ ẹwu alufa silẹ o ni ki awọn ijọ tẹlẹ on, o gbe ẹbiriki, o si kọri si eti ebute gbogbo ijọ gba tẹle lẹhin. Bi o ti de ebute, o gun ori ọkọ o gbe ebiriki o ju u ṣugbọn ebiriki koi ti de odo, nṣe ni Alufa ra lu'mi ki awọn ijọ to fa a soke o ti mu gẹ omi kan nwọn si wipe iwọ Alufa, ki tọ ẹ si eyi? o si dahun pe, mo fẹ fi ṣapejuwe ọrọ ti mo sọ fun nyin ni. Nwọn tun bere pe iwọ ha ṣiṣẹ apẹja ri? Ni Alufa ba nwo ilẹ.

No. 110

## Lagos - Tropani Creek Mail Service

The time-table published in Federal Gazette No. 37 of 4th July 1957, is hereby amended as follows :-

| PLACE | ARR. | DATE | DEP. | DATE |
|---|---|---|---|---|
| Lagos | — | — | 1000 | 1st & 15th |
| x Ejinrin | 1600 | 1st & 15th | 1600 | 1st & 15th |
| Epe | 1700 | 1st & 15th | 0600 | 2nd & 16th |
| x Artijere | 1300 | 2nd & 16th | 1300 | 2nd & 16th |
| x Aboto | 1600 | 2nd & 16th | 1600 | 2nd & 16th |
| Gbekabo | 1900 | 2nd & 16th | 0600 | 3rd & 17th |
| x Arogbe | 0900 | 3rd & 17th | 0900 | 3rd & 17th |
| x Ovenema | 1300 | 3rd & 17th | 1300 | 3rd & 17th |
| x Youngtown | 1600 | 3rd & 17th | 1600 | 3rd & 17th |
| Forcados | 1000 | 4th & 18th | 1200 | 4th & 18th |
| x Burutu | 1330 | 4th & 18th | 1330 | 4th & 18th |
| Warri | 1630 | 4th & 18th | 0600 | 5th & 19th |
| Bomadi | 1800 | 5th & 19th | 0600 | 6th & 20th |
| Tropani | 1700 | 6th & 20th | 0600 | 7th & 21st |
| Warri | 2000 | 7th & 21st | 0600 | 8th & 22nd |
| x Youngtown | 1600 | 8th & 22nd | 1600 | 8th & 22nd |
| Ovenema | 1900 | 8th & 22nd | 0600 | 9th & 23rd |
| x Arogbo | 0900 | 9th & 23rd | 0900 | 9th & 23rd |
| Gbekabo | 1300 | 9th & 23rd | 1500 | 9th & 23rd |
| x Aboto | 1800 | 9th & 23rd | 1800 | 9th & 23rd |
| Artijere | 2100 | 9th & 23rd | 0600 | 10th & 24th |
| Epe | 1600 | 10th & 24th | 1600 | 10th & 24th |
| Ejinrin | 1800 | 10th & 24th | 0600 | 11th & 25th |
| Lagos | 1200 | 11th & 25th | — | — |

Stops are made at places marked x and at any other intermediate points only if required.

No. 111

## Notice

The Offices of The Department of Co-Operative Societies, Lagos; have been removed to No. 12, Moloney Street Lagos. (Below the Ministry of Internal Afairs). The Telephone Number will temporarily, be that of the Ministry of Internal Affairs, Lagos 22724.

# Gbese ko dara

Ma a rin ma yan
Ma a rin, ma yan,
Iya mi ko je gbese o,
Baba si ko je gbese.
Sile Doherty.

Nigba aiye ijoun, ni nwon nkorin ti o wa loke yi. nitoripe, lasiko na ni okunrin kan olowo arakuyamu wa nilu Eko ti awon npe ni Doherty. Okunrin na je oniti o loja anu fun awon mekunnu a si ma ya won lowo. Sugbon awon ti o ya owo yi nigbati nwon ko ba ni owo na san, awon o ma fi oju pamo bi Doherty ba mbo, awon miran ko je gba opopo Alakoro koja nitori gbese ti nwon je Doherty.

Onigbese ko le rin fande gegebi o ti wu u, ijaiya ati ifoiya ojojumo ni yio ma wa fun pelu ero wipe olowo on yio ri on, ko si ni le ri fari kan se ni awujo awon egbe re, Bi enia ba je gbese ojojumo aiye ni yio ma fi ronu ko si ni le jade osan ayafi ki awon marindo oru. ki nwon balo ma fi ara pamo kuro loju olowo won. "Iyen nigba laelae ti itiju wa fun eniti o ba je gbese ki ise ni siko yi o).

Omo mi jeki nkoo logbon kan mase tayo gegebi agbara re ti mo jeki ohun ti Olorun se fun o te o lorun b'oba kan oro ti iwo yio fi je gbese okuku san ki o toro 'Gbese ko si esin ko si ad'oju tini ko si l'ode".

No. 73/S.2/Vol. VIII/486.

# Ministry of Education Western Region

## Vacancy for Illustrator.

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Illustrator in the Adult Education Branch.

Salary: Scale C(Y) 1,2: £408 x 18 – 462;
£486 x 24 – 510; £570 x 24 – 618;
£690 x 24 – 714; £744.

Entry point according to qualifications and experience.

For full particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 34 Vol. 6 Notice No. 693 of 25th July. 1957.

Closing date: For Candidates in the U. K. 15/8/57.
All other Candidates 22/8/57.

# AKIYESI

## Lagos Executive Development Board

PLANNING CONTROL

Enikeni ti o ba fe ra ile lati fi kole si, tabi enikan ti o nile ti o si fe kole sori re, tabi enikan ti o nile ti o si nfe tun ile na ko, ni Eko nihin, a gba awon enibe niyanju wipe ki awon to se ohunkohun rara, ki awon wa bere wo ni ile ise Town Planning Department ti Igbimo Lagos Executive Development Board bawo ni agbegbe ibe ti ri pelu eto ilu ti awon nse, ki o si le mo iru ile ti o ye ki o ko sibe.

Eniti o ba fe ki o kowe bere tabi ki on papa wa si Town Planning Department ti Igbimo Lagos Executive Development Board ni opopo Reclamation Road ni Eko lati agogo mejo si agogo mewa owuro lati ojo Monday titi di ojo Friday, ati lati agogo mejo si mesan owuro ni ojo Saturday

J. W. HENDERSON
Oleri Igbimo L.E.D.B.

# E jowo, e fi ona han mi

OLOTU. Jowo gba mi laye ninu iwe irohin re to gbadun lati fi oro yi lo awon okawe re wo, boya ngo ri ogbon ko lodo won. Bi oro na ti lo niyi:–

Mo ni iyawo kan, iyawo na si feran mi jojo, o bi omo meta fun mi, poun marun ni mo nfi sile ni owo onje gbogbo wa, mo si tun nfun on papa a ni Poun kan abo fun owo sina.

Ni gbogbo bi mo ti nse yi, ko dun mo iya re ninu, o si nko omo re wipe ki o ko mi sile. nko kuku mo ohun ti mo se fun. Omo re ni ki njeki on mu mi lo be iya re na, mo lo mo be e, ko gba, mo fi Poun meta bebe, iya na ko; mo kun owo na si poun marun, nse lo ko jade, o wipe ojo ti mo ba tun wa sile odo on, nse ni on yio se esu si mi lorun.

Omo re si laku wise on ko le fimi sile nitori ile odo mi ro on lorun pupo ko si wahala kan tabi idamu, pelu pelu oko on ko fi gba kan se on lati owuro di ale ri, beni on ko le fi awon omo on sile ki on lo de ile oko miran; kili e tun nfe ki oko na se, kini o gbe nigba nyin tobe ti mo fi mu wa be nyin ti e ko gba, o tun fi poun marun be nyin, e ko. Leri kini, kilo gbe nigba nyin tobe? Ni omo yi ba fon le iya re, iya papa a fon, o fi le omo ati oko re.

Gbogbo awon ara ile ati awon aladugbo ti o gbo ohun won, wa lati ba won da si oro na. Bi awon onilaja nwonyi ti nsoro na, iya iya o yi ko jeki nwon so o. O bere si se ileri wipe, on fe ki nwon wo oju on dara-dara, ara Owu ni on, awon ko si nsoro ki o ma jebe. Bi on ba wa ogun re ni Abeokuta ti on ko ri, on yio wa lo si Abaren, on ko si ko lati de Shaki nitori re.

Nigbana ni omo dahun pe iwo iya yi lo fi on fun okunrin yi, gbogbo owo ano, iya gbo, baba gbo, iwo nikan lo gba e, ayafi iku nikan lo le mu on fi oko on sile. On si fe ki o mo pe, on ni kan ni o bi; ko nse on lo fe daju re; iwo lo fe daju ara re.

Enyin okawe wa, idi niyi nitoripe, iyawo mi na si nwu mi; o si nte mi lorun; o mo ohun ti mo fe ati eyiti nko fe. E dakun e gba mi ni imoran, kini mo le se o.

Emi ni,

Abudu Latifu Oba

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo enyin Asoju Iwe Irohin wa nile Yoruba, l'oke Oya, nile Ibo, l'oke Okun ati nlu Oyinbo wipe enikeni ti ko ba fi owo ranse, ao ko oruko re fun Loya Eleti Ofe, ao ba se ejo ao si gba owo irin ese lowo won.

OLOTU



Bi o ba ngun keke ninu ojo, fi egbogi yi pa ibiti Lakuregbe nfun o nirora

ELECTRIC Balm

# ELETI QFE

A-NJU-WQN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI-QFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. IX. NO. 532, LAGOS, SATURDAY AUG. 10. 1957


## E Mase Da Aso-Ebi Mo

Ni opolopo igba ni awon Iwe Irohin ti nk'igbe wipe ki a da'wo aso-ebi ti a ma nda nibi ayeye nkan bi igbeyawo tabi ibi isinku duro nitoripe ko si ohun rere kan ti o ma nti idi re jade ayafi iwa ese si Olorun ati si ara-eni.

Lorekore ni a si ma nsi eyin eaia wa leti, paapa enyin okawe wa, lori oro aso-ebi yi, wipe ki e ja'wo kuro ninu apon ti ko yo—eyiti e ko ba fi ma a se iranlowo fun oloku tabi oniyawo, aso-ebi ti agbara ko ni ka, ti o je wipe opolopo ni yio ni-lati ma ya ojule kiri nitori a ti le da aso ebi, omo-binrin miran ti ao ma ro si eni abiyi ni yio gbe iyi re ta fise yeye nidi a nsure k'a le ba won da aso-ebi.

Nje nkan na ko ni dara bi o ba je wipe owo girimoyan ti a fi nda aso-ebi, ti a ba le da idaji re papo, ki a ko fun eniti o nse oku tabi iyawo gegebi iranlowo, awa gba wipe yio dara pupo bi a ba le si'wo ninu iwa aso-ebi dida ki a si ma a se iranlowo funrawa dipo re.

Aso – ebi dida ko dara o.

## Ako Oro

Iwo ore mi, jeki ako o ni ogbon kan. Bi Ohun-kohun ba wa ti ise Otito, tabi ti ise ohun owo; ti ise ododo, tabi ti o jasi ohun mimo, ti ise ti ife tabi ti ihinrere, iba se iwakiwa kan lo wa, tabi ohun iyin lo wa. mo wi fun o, ore, ki e ma gba awon nkan nwonyi ro daradara ki e to faramo.


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamo e wa ra QMQRELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

QMQRELA BABY MIXTURE

(Sile Meji Abo 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lodo

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Ijoye ti o se ti oba ro l'oye

Nigba aiye oba Idewu-Ojulari; okunrin alagba kan wa nilu Eko, ti nwon npe ni Akiwon. On lo ti je oye Olumegbon ri. ohun ti o wa fa a ti nwon fi gba fila oye kuro lori re ni wipe, Ogbeni Akiwon ti a wi ni awon eru pupo, sugbon awon opitan so wipe, okan ninu eru ogbeni ti a wi yi lo jale, nwon mu u; sugbon nitori ti o je giripa enia, o bo kuro lowo awon ti o mu, awon si lepa re titi o fi wo Iga Olumegbon.

Awon agbagba mu oro na lo si awujo Osugbo, Oloye Olumegbon paapa wa ninu Iledi nigbati nwon nfi oro yi sun igbimo. Nwon so fun ijoye na pe, se on na kuku fi eti ara re gbo bayi; kini o ri so si i. O si dahun pe, on ko ri nkankan so si.

Oloye Apena wa pase wipe, ki o mu eru re na ti o jale wa sinu Iledi nibin ni Oloye Olumegbon wa taku pe, rara! eyi ni ko le sese; ni won igbati nwon ko ti le mu nidi ohun ti o ji, nitorina on ko le mu wa.

Awon igbimo fi oro na lo oba Idewu-Ojulari, nipa esi ti Olumegbon fun won. Awon opitan so wipe oro na bi oba ninu tobe ti o fi ranse pe Oloye na. Bakanna ni Oloye na taku. Oba fi oro na han awon ijoye ilu ni Ose Iga awon ijoye l'o sepinnu lehin ti Olumegbon taku wonle, pe ki oba gba fila oye kuro lori re. Nitoto, oba gba fila oye kuro lori re.

Nigbana lo salo si Okun Aja, awon ijoye tun ranse si pe Oru re nmu awon nibiti o gbe wa; nitorina ki o fun won laye ni o ba salo silu kan ni eti Ilu Epe ti awon npe ni Egbo.

Awon Ijoye tun pe e pada wa sile, s'ori oye re nigba aiye oba Akitoye nitori ti emi ijoye na gun jojo.

## Owe ile Yoruba

O wu Aguala pe ki o mo-le to Osupa, Olorun oba ni ko fi fun u. Ilara alaju lo nmu won gbajo lo nmu won seso,


No. 17/Vol. x/173.

## "Teaching of History" Exhibition

**Inspectorate Bookroom**

NEW COURT ROAD, IBADAN.

(Training Colleges and Secondary Schools)

July to August, 31st - 2 p.m - 6 p.m.

All teachers are invited to see the exhibition of books, pictures, charts film-strips, available for history teaching in schools and colleges.

IMPROVE YOUR TEACHING. SEE WHAT YOU AND YOUR PUPILS CAN DO.


## ANFE ASOJU

A nfe Asoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Qfe lati fi kun awon Asoju wa ni awon ilu ti a daruko ni isale wonyi:-

Abeokuta, Ijebu-Ode, Ijebu-Igbo, Ile-Ife, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kowe si Olota Iwe Irohin Eleti-Qfe, 28, Kosoko St, Lagos.

# Talo Ni Obo Yi O?

Ni owuro ojo kan ti ojo nro, okunrin akowe kan mura lati lo sibi ise sugbon ojo ko jeki o lo, o wa yoju wo ita lati wo bi ojo na ti po si; beni o taju kan, o ri obo (Haya) kan tabi eyiti nwon npe ni Edun Olokun, ti ojo ti paa, o le gongo, o si ngbon, nitori ti otutu nmu.

Akowe na nawo si, o si tore mo apa re. O gbe wole lo, o dano fun, o si fun ni onje, ibe lo fi obo yi si ti o lo sibi ise. Nigbati o npada bo nse ni obo yi lo pade re, o si fo mo ni apa.

Okunrin akowe na wa gbe lo si kotu olopa pe, bayi-bayi ni on se ri obo yi sugbon on ko mo eniti o ni i. Bi a ba ri eniti o ni i nje on niyi. Awon olopa ni, ki o si ma lo toju re.

Lehin osu mesan ti akowe na ti ntoju obo na ni Ogbeni kan so pe on ri obo on he, lo ba tu okun re nibiti nwon so si, ibe ni akowe ti mu ni ole, riti-riti lo ba di kotu, o diwaju Adajo, enikini so pe ti on ni obo yi, enikeji ni ti on ni obo na.

Oro na niyi enyin okawe wa, e bawa dajo na ki adajo to wa da fun wa.

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re.



# OVALTINE
## ni
## Elere idaraya nmu

Nitoripe Ovaltine nfun ni ni agbara ti oduro O si tun nfun ni ni isegun. Ere idaraya a ma gba gbogbo okun ati emi lopolopo - Ovaltine a si ma fun ni ni agbara ara titun werewere ati agbara pelu okun.

Ogbon ero ni a fi se e lati inu awon eyin, eso lougbin, wara, ti a si fi nkan elo imarale pelu re. Ovaltine gbadun ni mimu o si je onje to baramu pupo, gbogbo awon elere idaraya lo nmu nibikibi. Fi Ovaltine se ohun ipanu lojoojumo ati lale ki o to lo sun.

*Ovaltine je onje ... [illegible] ... 1932 ... Olimpik. Awon elere idaraya ti Olimpik a ma mu Ovaltine ... [illegible]*



# OVALTINE
## wa fun agbara at okun

## Ikede Odun Agboniregun 1957

1. Eyiyi ni lati ṣe ikede pe Odun Agbọniregun di Ogun'jọ oṣu Ogun 20th August 1957.

Olikaluku Ilu ni yio ṣe Ajọyọ ọdun Agboniregun yi ni ilu tire li ọjọ kanna ti a wi yi gẹgẹbi ipinnu wa - Ogun oṣu 20th August 1957 Ọdun aya'bo. Aṣe.

**ỌPẸ, EBẸ, & IWURE PATAKI FUN OMINIRA**

2. Ninu ipade Ajọyọ ọdun Agbọniregun ti 20th Ogun yi ohun keji ti ao ṣe nipe ao dupe fun ominira ti agba. Ao bẹe-be fun ifẹ ede mule ṣinṣin fun Ijọba wa ao wa fi ire pataki pari re fun awọn Olutọ'kọ Ijọba wa pe ki Ọrunmila-Oduduwa fun ra Rẹ maṣe olutọ wọn ni gbogbo igba fun ire ati pe ki Ijọba wa le di Olokiki bi ti Kutukutu Owurọ.

Gbadebọ Dosunmu.
Olulana Ijọ ti Ọrunmila
ati
Akọwe Gbogbo-Gbo
Ajọ Babalawo-W.A.







## Kere o!

A ti ni origirigi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tokutọkọ tobinrin. Tete wa ra tiɛ, k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.


## AKIYESI PATAKI

**Enikeni ti o ba fe ra Iwe Irohin Eleti - Ofe Ki o lo si Idi Moto, Ogunpa, Tabi Lodo Asoju Wa, Ni 107, Oke Padi, l'egbe Sesi Aguda Nilu Ibadan.**




Awon gbajumo enia gba pe...



Eyi ni lati je oti "Star Beer!" O soro lati ṣi iru oti larger atata bẹẹ mọ. Iri rẹ didara ati ti tutu ti nta-wanin-wanin je ami bia ti o dara julọ — Star ni ni!
Agb'oti—fun mi ni Star Beer meta ni i!

OTI

# STAR



l'o je eyiti o dara ju!
-Beni Sammy Sparkle wi.



*OTI BIA ti o dara ju nfe ohun ti o tun ju eelo atata, lo—o nfe egbon ati imo. Okun eele oti ati bali ti o dara julo ti nwon nlu wa lati ilu okere ni nwon fi se e. Awon ojogbon ponti-ponti ti o wa lati ilu Oyinbo ni o nse Star Beer olokiki na. O gba iyi pe oun ni asiwaju oti lager ti nwon fi igo ro ninu idije British Empire ati Commonwealth ti nwon se ninu odun 1954. Oti ti o gbadun ju ti o tutu lona ti(o)ji ni itelorungidigidi ni.*

# Okuwobi Fo Ese Mefa, Esun Mefa.



GLASGOW. Lasiko kan ni a gbọ wipe ko si awọn ẹiyẹ enia ti o le fo ẹsẹ mẹfa. Nigbati o ṣe ni a gbọ pe ọmọ ilẹ Nigeria kan ti a npe ni Chigbolu fo ẹsẹ mẹfa ati ẹsun mẹrin abọ lati gba na, a koiti ri ẹnikan ti o le fo tayọ eyi ni gbogbo agbaiye.

Laipẹ yi ni ọgbẹni kan, ẹniti a npe ni O. Okuwọbi, ọmọ ilẹ wa nihin, on lo fo ẹsẹ mẹfa ati ẹsun mẹfa nilu Glasgow, eyiti ẹnikan ko lala lati fo ri. O fi ẹsun kan abọ tayọ ti Ọgbẹni Chigbolu. Ẹ kare, ẹ ma tẹsiwaju bi ọmọ ogun Onigbagbọ.

Siwaju-siwaju lọpa ẹniti ayin yio ma re si o.

# Idahun Si Ibere

(O bẹrẹ ninu Iwe wa ọsẹ tokọja)

Ọrẹ wa, Ọlatunji, njẹ awa le tun gba ọrọ rẹ yi gbọ bi? nipa ọrọ ti o sọ wipe ki emi sọ bi mo ti jẹ ni Owu fun yin. Bi mo ti jẹ niyi. Mo jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Owu ti nwọn bi si Owu ti nwọn si wo ni Owu. Baba mi to yọ yin ati Baba ti o bi Baba mi joni ni oju orukọ Baba mi han nilu Owu bẹ sini ti Baba ti o bi Baba mi ko mu rara. Iwọ yio ma gbọ orukọ mi ni isalẹ iwe yi. Iwọ yio si mọ wipe ọrọ ti o bere wipe nigbati mo ri ohun ti ko ba oju mu kiniṣe ti emi ko ṣe atunṣe? Esi mi si ẹ niyi: Nigbati a ri wipe edeaiyede na de ti o si han, ni o mu mi kọ si Iwe Irohin ki gbogbo ọmọ Owu ti o wa kakiri le gbọ ohun ti o nṣẹlẹ, ohun ti o si mu mi ṣe alaye edeaiyede yi sinu Iwe na ni wipe ki awọn enia le tete dide si edeaiyede na ki nwọn si le tete pa ina rẹ molẹ.

Nipa ibere rẹ ti o sọ wipe kini awọn Ilu sọ wipe awọn fi owo poun kọkan ti nwọn da ṣe? Awa ko mọ, na ni a ṣe sọ wipe ki ẹ ṣe alaye fun wa sinu Iwe Irohin yi, elo ni owo poun kọkan ti gbogbo wa ti nda lati ọdun kẹfa wa jẹ? ṣugbọn dipo ki ẹ ṣe alaye yi nṣe ni ẹ fi ẹtẹ silẹ ti ẹnyin npa lapalapa, nitoripe ki a ṣa ti gbọ wipe on na sọrọ sinu Iwe Irohin. Nipa ọrọ re ti o da wa ni ebi si wipe kini ṣe ti awa ko ṣe bi Akapo Ilu Owu lere? Ọgbẹni Ọlatunja ṣebi Eko ni iwọ wa ni ọdun ti o kọja May 25th 1956 nigbati nwọn bere nipa re kini ṣe ti e ko ṣe la wa ni oye Akapo na ati awọn Igbimọ Ilu Owu na ati ni ọdun yi na titi wọn fi ba ija tuka ni Ipade. Inu wa yio dun bi Ọgbẹni Ọlatunji ba le sọ orukọ Akapo fun wa ati orukọ enia pataki mẹta ninu awọn Igbimọ na. Aimọ ko ni si fun gwa na mọ. Awa yio si dupẹ pupọ ni ọwọ rẹ awa yio si ka ọ kun enia pataki ninu Ilu Owu.

Ọrẹ wa Ọlatunji kini wa de ti iru ọrọ ba yi fi jade ni ẹnu rẹ si wa bayi wipe enia adaluru ati ọlẹtẹ ni wa. Kini wa fa ohun ibinu? Ma binu rara. Esi ọrọ ni ki o ma mu fun wa dada ki gbogbo enia si ma gbọ ni agbọ ye. Nitorina, maṣe binu rara o. O sọ wipe ki emi da ọgbọn ati gbogbo ibiti awa yio de, Igbimọ yin ti de ibẹ. Ọrẹ wa Ọlatunji ọrọ rẹ yi ti han wipe alaimọkan enia ni ọ, ṣugbọn bi o ba ku abuke ati aburo, nwọn a ma pe ara wọn ni otọ-rọrọ.

Nipa edeaiyede ti mo wipe wipe ko di giga; iwọ Ọgbẹni Ọlatunji fi nye mi wipe ki emi da ọgbọn inu mi ki ọrọ na le di giga; emi fi han wipe ọmọ bibi ni Owu ni emi nitoripe ni Ilu ti nwọn ba bi enia si, gbogbo nkan ti o ba nṣẹlẹ ni ibẹ ni o yẹ ki enia na mọ. Ọgbọn ti ti ọrẹ wa Ọlatunji sọ wipe kinda, ọgbọn na ti ṣẹlẹ, eleyi si jẹ nkan ti o han si ọ gbangba nitoripe ni 2nd July, 1957 ni nwọn lọ mu awọn Igbimọ r mejo lọ si Ilorin.

Ọrẹ wa, ọrọ rẹ ko mu ọgbọn wa. Tani eniti o da poun kọkan (£1) sibẹ.

Mo duro bayi,
Emi ri
Raimi Alabi Jimọh

# Asoje Oro

Aja agba ni'gbo
Oke Ijan mi titi:-
Talo le so itumo
re fun wa.?



# Alapara Ibadan Nki Yin o

Oke Foko,
Ibadan

Alapara Ibadan nki yin o! o ni ki e lowo ki e bi omo — sebare Ogunpa ko ni gbe yin lo — Oke'Badan ylo di eru re yin ki e ba ri chun fi se gbegiri je.

ADEGBOYEGA

Nigbakan nilu Abeokuta ti ijoba atata wa ni owo Egba-Egba United Government ni nwon npe nwon nigbana; won ri pe bi ise Ijoba ba ni lati lo dede, o ni lati ni akowe ti o gboju. Oruko akowe Ijoba ti won gba nigbana ni mo fe so ore mi Ogbeni W.S.A. Warren akowe Ijoba ibile Ibadan (I.D.C.) ti a sese gba lati ilu Oyinbo wipe ki o wa ba wa se

Ni oni, lojo awon iya wa, ati baba wa, lomode lagba, emi Alapara Ibadan so iwo Ogbeni Warren ni

ADEGBOYEGA WARRIN

(Warin-you are going to walk and work). Oruko na a mo ori o, sugbon mo fe ki o mo wipe ojo ilu Ibadan di koko. Odumare a je ki o le tu koko na.

Emi Alapara Ibadan gbo wipe ise owo re si gebi ase-igbimo ilu po jojo. Opolo re si jinna fun iwe ofin, o si wa kori ra ngaba-gebe ase-igbimo nla Iyen wu mi o! Eku sho o

ORE MI ESAN DA?

Eiye ko tile so fun eiye pe oko abe lati ore mi Ogbeni Victor Owolabi Esan—omo Badan ti o ti nse ise akowe Igbimo ni Oke Mapo ri. Ekun nijo mo ara won ri. Boya o gbagbe wipe emi Alapara je ikan ninu awon omo Ibadan (ni Eko) ti o ki o ku oko nigbati o ti ilu Oyinbo de ni odun kejo sehin, Agbada ni mo wo; mo si de fila abeti aja. Aha emu mi lo tobi ju nijona, mo si joko l rin Ogbeni S. A. Odebunmi ati E. A. Fakayode. O ye ki o so fun wa ki o to fi aga ke. Eto ilu di owo yin o.

ESE YA JU MOTO

Ore mi, boya o ti de Eko tipe. Ni ilu Eko nisisiyi, ka fi ese rin o ya ju moto lo o. Kilo fa? Ojo aro-aida lo fa sababi. Mo ni ki nse bi a ti nse ni Ibadan, mo lo si ile elemu; Awe ni o di ogunjo ti on ti de oko. Ojo ko le. Gbogbo ile lo wo tan, awon moto wa ara bi opun.

Bi o ba nlo s'Eko ki o mu ewu apeji lowo, ki o si di agunmu mo eru. Otitu nbe l'Eko aromisa legbe legbe – ile ogbon.



AKADAN NERVIGORA

Ogun eje pataki fun imarale agba ati aremo pipe fun awon alaya pupo. O dara fun inarun, eje dudu, isokun oju, gbigbon owo, ailesun, ailokun ninu, ati irufe arun bawonni. O je ajidewe fun awon ti agbara won ndinku. On na gan ni okunrin yi lo ti o fi di "Afese kun bi ojo." 5/6d. pere pelu owo oko 1/6d e.g. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores**
112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute-Metta.
Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.

Let's have MUSIC! – HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



*Read this list of popular titles*

JZ 6077-Omosola Savage/Igba Laiye
" 6078-Aiye Akamara/Iwa Rere Leso Enia
" 6079-Gbo Adura Wa Baba/Irele Lo Laiye
(Rosey Show Mambo Orch)
" 6080-Gba Wa Lowo Ota/Ibaru Oluun S. O. A. Ladipo and His Keramic Group
" 6082-Olorun Lo Laiye/Feso Jaiye
" 6083-Shugbola/Wellington Ade-Ade & His (Juju) Orchestra.

JZ 6088-Owo Lowo Agbara Ko/ Abiba Alaso
" 6087-Ori Lo Yomi/Saka Ilorin Amin Olaribigbe & His (Sakara) Band
" 6089-A Gbere Wa De/Awon Kokokoko–
Taibas Abuna & His (Apala) Band
RJZ 100-Mo Pami/Zambesi
(In Afro-Cuban)
RJZ 101-Bowo Ba De/Adaku (Ibo)
RJZ 102-Ma Doyinbo/Igbuem Iwem
(Itsekiri) (Ibo)

*Sold by all the best stores*

"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow Label* RECORDS

HIS MASTER'S VOICE

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 23370